# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idahun Si Ibere Qlaonipekun

Idahun si ibere Qgbeni Mofolorunsọ Qlaonipekun, Oke-Offa Ibadan ti on paapa fi sọwọ si wa niyi:—

1 Iwe ti o wa ninu Bibeli jẹ 66. [39 ni Majẹmu Lailai 27 ni Majẹmu Titun]

2(a) Ori ti o wa ninu Bibeli jẹ 1,189.

2(b) Ẹsẹ ti o wa ninu Bibeli jẹ 31,175.

3 Ori iwe ti o gun julọ ninu Bibeli ni Orin Dafidi, ori 119.

4 Ori ti o kuru julọ ninu Bibeli ni Orin Dafidi, ori 117.

5 Ẹsẹ ti o gun julọ ninu Bibeli [Yoruba] Kronika kini, ori 26 ẹsẹ 15.

Ẹsẹ ti o gun julọ ninu Bibeli [Ede Oyinbo] Esteri ori 8 ẹsẹ 9.

6 Ẹsẹ ti o kuru julọ ninu Bibeli ni Ihinrere Johanu ori 11 ẹsẹ 35 [Jesu sọkun].

7 Orukọ ti o gun julọ ninu Bibeli ni Maher-Salal-has-basi Isaiah ori 8, ẹsẹ 1.

8 Orukọ ti o kuru ju ni "Ai" Joṣua ori 7 ẹsẹ 2.

9 Iwe ti o wa ni idaji Bibeli ni Orin Dafidi ori 118 ẹsẹ 8.

10 Ori iwe meji ti o ba ara wọn dọgba ni Awọn Qba Keji ori 19 ati Isaiah ori 37.

11 Rebeka ni o fi ara rẹ gegun ni Genesis ori 27 ẹsẹ 13 ati awọn Ju ni nwọn fi ara wọn gegun tiran-tiran ninu Matteu ori 27 ẹsẹ 25 "Nitori Jesu Oluwa".

Awọn ti orukọ wọn wa ni isalẹ yi ni o dahun ibere na ṣọwọ si wa.

1. M. O. Adeleke, Igbẹti - Ilọrin mọ mejejila, ṣugbọn idahun rẹ si ibere kejila ko kun to.

2. Awoko Jesu, Ibadan mọ mẹjọ, ko mọ mẹrin No 2[a] ati [b], 9, 10, ati 12.

3. Joshua F. Adeọba II Oluj mọ meje ati abọ, ko mọ No 2[b] 7, 9ati 12.

4. Theo. Babs. Akinmusire Ikere Ekiti mọ mẹrin pere No 1 3, 4, ati 6.

5. Sam. Adepoju Qlatunde, Ikirun mọ merin pere No 1, 3, 6 ati 11.

6. Tijani Ojẹwunmi, Itẹsi Abeokuta, mọ mẹta ati abọ pere No 1. 2[a], 4 ati 6.

7. A. K. Ikubọlajẹ, Iji - Owu mọ meji ati abọ pere No 1, 2a ati 6.

8. Temidere, Mọkọla Abeokuta, mọ meji pere No 1 ati 11.

9. Paul Qbarọye, Odi - Olowo mọ meji pere No 7 ati 11.

10. E. O. Afọlabi, Ilugun, Abeokuta ko mọ ẹyọ kan nibẹ rara.

Ibere yi ti jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 27/7/53.

A ki onibere na ati awọn ti o dahun ibere na ku iṣẹ o. ... a
OLOTU


Ẹ MA A KA A
Iwe Irohin Yoruba
NIGBAGBOGBO FUN
IROHIN ALADUN




Eyi ni Ijoko awọn Ikọ Ẹba Ariwa Nigeria [Hausa] ni ọjọ ti nwọn bẹrẹ ipade Igbimọ atunṣe eto iṣẹlu Nigeria ni London.




ABIYAMỌ, ETI RẸ MELO?

Abiku ọmọ nda ọ l'amu bi?
Awọn arun wọnyi hẹ ayọ ọmọ rẹ lọnu bi?

AIPERI
ỌRẸRẸ
INU-IWỌ
OSI
IGBONA
IKỌ
IGBẸ-ỌRIN
OTUTU
IBA
JẸDIJẸDI

ati orisirisi awọn arun miran ti ima yọ ọmọde l'enu ni igba EHIN HIHU. Lọ ra "Yaro" awo igba arun ọmọde ni fun gbogbo awọn arun ti ima yọ ọmọde lẹnu.

"YARO" ko pe mej ni gbogbo ilẹ Nigeria.

Ki iwọ ki o ri i pe orukọ "YARO" ni o wa lara igo na ki nwọn ma ba ta idamọdi egbogi miran fun ọ.

Fun Arun Wosewose, Lakuregbe Ati Orisirisi Iwora

Elasto

THE BIOCHEMIC TABLET

E ti ṣe ti o fi dabi[?]ẹnipe arun miran wa ti ki i gbọ oogun! Ohun ti o nfa a ti a ko ti lero pe on ni, ni a kọ gbangba si isalẹ yi "AIṢAN - YIKA - ẸJẸ" [BAD CIRCULATION]. Egbogi titun ti o ntiṣẹ si oluwarẹ ko le fi ri irora kankan niyi "Elasto". Ti ẹnia ba lo egbogi yi ti o ba ti ni arun lakuregbe, ẹsẹ wiwu, wosewose ati orisirisi arun ti aiṣan-yika-ẹjẹ ti nfa wa, gbogbo rẹ ni egbogi yi yio gbọn danu bi idan, gbogbo agbara ati ilera oluwarẹ a wa di titun. Tete lọ ra egbogi "Elasto" ni ṣọba egbogi ti o ba ri i, wa si fi ṣẹnu ara rẹ jẹwọ pe ogun atata ni egbogi kekere yi.

AKARA TU 'EPO

Iwe kẹfa ati keje Mose ni ede Yoruba: pẹlu iwe agbeyanu Sọjọmọni ọmọ Dafidi ati ọpọlọpọ Asiri miran ti awọn Woli lailai ti bo mọlẹ wa di ohun Kika ati Anfani fun olukuluku.

Asiri orukọ Qba mimọ Olodumare. Asiri bi a ti ṣe le ba awọn Maleka mimọ sọrọ lojuk rọju tabi loju iran. Hantu [Seal] fun Iriran, Abo Asiki, Itaja, Asiki Imọ, Asiki Ijọlawaju mbẹ ninu rẹ.

Iwe yi ni a npe ni ede oyinbo "The 6th and 7th Books of Moses". Sile medogun pere ni [15/-] Fifteen Shillings. Sare ra tirẹ ki o to tan o.

A si tun nta orisirisi Oruka Owo, Oruka Ifẹ, Oruka Qja tita ati ọpọlọpọ oruka ajọ ti iwe yi ko le ka. A ṣe ikede yi fun awọn ọmọ-ẹgbẹ ati awọn ti o fẹ di ọmọ ẹgbẹ Awo Imọlẹ ti a npe ni The White Brotherhood Lodge ni ede Oyinbo, Ki nwọn bere fun Iwe Irohin Ẹgbẹ ti o wẹẹ jade [OFẸ LAFUNNI]
KỌ IWE SI,—

OLUWO
29, Ramos Street, Idi-Oro Yaba, Nigeria tabi
36, King George Avenue, Yaba Nigeria.

E Polowo Qja Nyin Sinu Iwe Irohin Yoruba

